The Chief Secretary to the Governt

# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. VI. No. 270. SATURDAY, APRIL 14, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

NIGERIA 1—MAY 1928



## White's Radical Gonkiller.

(NATIVE.)

[*A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.*]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

**N.B.**—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

Victor White, Esq., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

Price: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

[*Fun Atọsi lailai ati titun.*]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nje ki o ri aye wu arun mi silẹ.


Akinkunmi

"AWA O MA JO, AWA O MA YO, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ẹgbẹ, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

*Office* :—

No. 3, Docemo Street.
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

---

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

# Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, Işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.

---

**Are you a Mechanic?**—If so you must want Tools, now or soon!

**Do you intend to put up a house?**—Then you will require Builder's Hardware!

In either case you cannot do better than call at

## B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

---

## J. C. VAUGHAN

Ti ile ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna: bi o lẹ di awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ri nibẹ:

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹgẹ l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kanaa

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Ati-Ajanaku lọjọ to ti pẹ: bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai! bi o ri orişirişi Ọko ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere ibẹ.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

ALAGBARA LO L'AIYE.

Ẹnu ko ni ṣai ya ẹnikẹni ti o ba di gbẹrẹ lọ si Ebute Ero lati ri pe ogọrọ ninu awọn obinrin ti nwọn ta 'ja ni awọn Municipal ti gba lọ si Oke Arin, nibiti a gbọ pe Ijọba nbu ilẹ fun wọn lati kọ isọ wọn si fun ponun kan (£1) oṣu fun isọ kọkan ni hihaya: bi eṣu ni awọn ero nwọ ni ọja titun yi: ohun ti o si ya ni lẹnu ni pe kaka ki Ijọba jẹki awọn obinrin wọnyi ma lo ilẹ Oke Arin yi lọfẹ dipo Ẹhingbẹti ti Ijọba ti le wọn kuro ni ọdun diẹ sẹhin; owo lọwọ ni Ijọba nfi hihaya ilẹ na ṣe fun wọn. Ọrọ gbogbo lori ṣile ni nkan da nisisiyi, ere elo ni awọn enia wọnyi njẹ ninu ọja wosi-wosi ati nkan jijẹ ti nwọn nta nibẹ o? Pagidari! oju anu Ijọba ha ti fọ bi? Ka ma ri! ka ma ri!!!

IGBA ARA LA MI NBURA.

Diẹ ṣiun lo ku larin ọsẹ yi ki mọto meji fi pẹki ko pẹki 'ni arin ọja Ita Faji; a ṣebi awọn Alabojuto Ọpa Ọba ti yan awọn Ọlọpa si ibẹ ri lati ma ṣe abojuto ewu awọn mọto, kini ha tun fa sababi ti a tun fi ṣi wọn nipo pada ti a ko fi le ri Ọlọpa kan lọjọ yi ti yio dabobo awọn ewu mọto?

BO PE TITI OGUN ỌDUN A KU ỌLA.

Lati bi ọsẹ meji ni gbogbo ilu ti gbojikan pe ni ireni lori ni nwọn ma sọlu ẹjọ Ẹni Aiye-nfẹ Ọba Eṣugbayi Eleko ni ilu Oyinbo ni ibi ti gbangba gbe tẹju lati ma yọ ina iwe ofin lẹnu bi Ṣango. Adura dọwọ ilu firifiri, ki Sati le jẹki atubọtan ẹjọ nla yi le ṣoju t'ku-t'ẹiyẹ.—Ẹ ṣe Asalatu l'Onișẹ nla.

IWE-IHAGUN DOHERTY (OLOGBE). KAI! ỌGA NI DOHERTY.

Ninu ọsẹ to kọja ni nwọn ka iwe-ihagun Ọgbẹni Josiah Henryson Doherty: eyiti o ta si wa leti ninu rẹ ni pe o ni ki nwọn fi ọdẹgbẹta ponun (£500) fun ẹnikọkan ninu awọn ọmọ on ọkunrin ti oyun-inu ti aṣẹ-idi; adọtalerugba ponun (£250) fun ẹnikọkan ninu awọn ọmọ on obinrin ti oyun-inu ti aṣẹ-idi bakanna. A gbọ pe o ni ki nwọn ma fi ponun mẹta-mẹta fun awọn obinrin on lọṣọṣu fun ọdun mẹta gbako; awọn ti o ba ni ẹbun ẹkọ ninu awọn ọmọ on ki nwọn ran wọn lọ si ilu Oyinbo fun ẹkọ; ati ẹnikọkan ninu awọn ọmọ Bishop Howells ati ọmọ Ọgbẹni F. G. Martins, ki nwọn ran won lọ si ilu Oyinbo fun iṣẹkiṣẹ ti nwọn ba fẹ lọ kọ nibẹ. O ni ki nwọn ma ni awọn onigbese on lara ti ko ba ri owo san; ki nwọn ma fi awọn ile on haya, ki nwọn ma fi owo wọn tọju ẹbi, fun ọkunrin ti o ba tẹ gbeyawo tabi fun obinrin ti nwọn ba fẹ sin fun ọkọ. O ni ki nwọn fi ọgọrun ponun fun Ijalẹ—kori-kosun rẹ.

A gbọ pe Ọgbẹni F. G. Martins, Ọgbẹni Ṣogbẹsan ati Ọgbẹni Carrena ati awọn ọmọ rẹ mẹta ọkunrin ni o fi ṣe baba-nsinku. O ni ki nwọn ma ba ọwọ bo, ṣugbọn ọmọ rẹ Adebayọ Doherty li a gbọ pe o ni ki o ma ṣe Olutọju ọwọ rẹ. O ni ki nwọn san iyoku ileri on fun Ṣọṣi Alagogo (*Christ Church Pro-Cathedral*), ki o ba le fi pe ẹgba ponun (£2000) ti on ṣe ileri fun Ṣọṣi na. l'ẹtẹsi rẹ ti o wa ni Campos Square ati ti Massey Square ati ti Ebute Mẹta ti gbogbo awọn ẹbi ni.

Ọga ni Doherty. Ki Ọlọrun ki o dẹlẹ fun.—Amin.

*From Eleti-Ọfẹ of 11/4/...*

## RUKERUDO LORI TEMBELEKUN ILU.

Lati ọwọ Kekere Awo.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

O dabi ẹnipe awọn ẹlomiram mbẹ ni arin ilu yi awọn ẹniti o fi ara wọn joye Aṣọtẹmaru tabi onitẹmbẹlẹkun ti ero ori wọn ku diẹ ki o pe, gẹgẹbi ọmọluwabi, irufẹ ero ti o mbẹ lori mọjeṣin, boya nigbati ẹlomiran ti ri ẹni ran on lọ si ilu Aganyin, ilu Sare tabi ilu Oyinbo lọ kọ iwe, ti obi rẹ ti run 'pa run 'sẹ le lori lati mọ iwe ati lati ko ọgbọn, eyiti ẹlomiran ti fi nṣe fuja pe ko si irufẹ on mọ nitorina ero ori rẹ ti pe, agbẹdọ arara·

Bi o ba tilẹ jẹ wipe ẹlomran mọ iwe daradara ti o si ni ọgbọn ati lakaye lọpọlọpọ ati ni iba ti ọmọluwabi ni lati ni lọna omiran ati nipa mimu ilu sori kodo ati rukerudo, a ko le sọ wipe ero ori wọn pe to.

O nwu ọpọlọpọ enia lati ma ṣe ilu "OṢELU" ati lati ma ka ara rẹ kun ẹniti o mọ ẹtọ mọ ẹyẹ ti o si mọ yayi ti o dara lati ma ṣe nipa ọran ilu ṣugbọn nwọn ha duro kọ bi nwọn tiṣe nṣe ilu ni ilu ibi ti nwọn ran wọn lọ kọ iwe—ni ilu oyinbo?

Ki iṣe ẹniti o ba ni owo ti o si dukiaya ọpọlọpọ ati ẹbun iwe nikan lo le ṣe ilu.

Ni ilu oyinbo ọmọde kekere le ṣe ilu ti o ba mọ iwọn ara rẹ, a ngbọ wipe *Lord! Lord!!* mbẹ ni ilu oyinbo ki iṣe ẹniti o kuku ni owo lọwọ nikan ni kan ni nwọn kuku npe ni *Lord* tabi ti o le sọrọ ni *House of Commou* nibiti awọn ọlọla ilu oyinbo gbogbo nsọrọ nipa ilu ati nipa oriṣiriṣi ọrọ omiran

Ẹniti o ba mọ oye nipa ṣiṣe-ilu ti lakaye ati ọgbọn ori rẹ si pe perepere le jẹ *Lord*, ki iṣe ọgbọn arekenda ọgbọn tẹmbẹlẹkun, ogbọn rukerudo ani ogbọn ti o le tun ilu ṣe ti o le mu rere ilu dani, ẹniti a mbu ọla fun lo njẹ *Lord*, bi o ba jẹ wipe nipa nini dukiya lọwọ li a fi le pe enia ni *Lord*, bi ọpọlọpọ olowo ti mbẹ ni ilu oyinbo bẹni ọgọrọ akuṣẹ mbẹ lọhun pẹlu, bẹni ki iṣe gbogbo awọn *Lord* ti o mbẹ ni ilu oyinbo yi tan, ni nwọn kuku lowo lọwọ bakanna tabi ni nwọn kuku bi nigba kanna, bi ọwọ wọn ba ju 'rawọn lọ ti nwọn ba si fi ọjo diẹdiẹ daiye sin 'rawọn, ani ti ika ọwọ wa ba si ti yọri diẹdiẹ ju ara wọn lọ, nitorina awọn *Lord* gbogbo ti a ngbọ orukọ wọn le ju ara wọn lọ.

Ologbe Lord Leverhulme, boya bi a ba ni ki a da a silẹ ki a tun ṣa a, *Lord* miran fẹrẹ le gba ni aburo lọna talantin, ṣugbọn ki o to lọ jẹ Ọlọrun ni ipe, o fẹrẹ dabi ẹnipe on nikan, ni a bi si ilu oyinbo, boya bi a ba tun wa idi ifin koko a kale ṣai ri *Lord* miran bi irẹ ti o fẹrẹ le fi owo ra gbogbo owo rẹ pa porongodo ti a ki yio gburo rẹ mọ firinfirin. Gẹgẹbi on tikalararẹ ti daba ni igba aiye rẹ nigbati aiye tẹ ẹ lowọ tan pe on fẹ ra gbogbo—ilẹ enia dudu, tile-tile, toko-toko, tonatọna pẹlu, iyoku di iregbe, o fẹrẹ le sọ wipe ki Ijoba Igẹsi jẹ ki on ra gbogbo ọmọ abẹsẹ wọn ni ilẹ enia dudu tiran-tiran, ki on fi wọn ṣe iwọfa ki nwọn ma ṣiṣẹ fun on ni oko, bi o ba jẹ wipe aba ti o da a, Ọlọrun fi tirẹ ṣe.

Nipa eyi awọn ẹlomiran kan wulẹ na owo lọ si ilu oyinbo lọ kọwe ni, nwọn ko gbero lati fi iwe wọn ṣe ilu wọn lanfani.

Ọpọlọpọ ẹniti o si nka ararẹ si nkan danindanin, ti o gbọn diẹ lati fi ṣe eto ilu ti ko tilẹ tẹ okun Aganyin nitosi nihin ri, ti sọ ori ilu Eko kodo lori ọran tẹmbẹlẹkun.

Awa duro lati ma tọ ilu sọna ẹniti o ba nda ruke-rudo nipa tẹmbẹlẹkun silu a duro lati ba dikarewa, ni ona ti ẹto ilu, ki iṣe ni ọna iṣubu, ṣugbọn ẹniti o ba nfẹ iṣubu fun ilu dajudaju ilu yio leke rẹ bi ikeke ti nleke igi, ti oju oro si nleke odo pẹlu.

A nja fun rere ilu ẹwẹ a si nja fun awọn ọmọ wa lẹhin ola, nitorina, o yẹ wipe ki a ma fi oye ọran ilu Eko si waju nyin, ohun ti o ba si jẹ ohun pataki ti o ṣẹlẹ ni sa laelai, a o ma fihan diẹdiẹ lẹkẹkan.

Lẹhin ti ọtẹ aiye Ọba Kosokọ ati Akitoye eyiti Ọlọrun fi Ijọba Igẹsi ṣe alatunṣe tabi onilaja—a dupẹ fun Ijọba Igẹsi, a si ṣe adura bayi pẹlu —Alabukun ni fun ẹnyin onilaja—gẹgẹbi Jesu ti wi, ṣugbọn ti a ba sọ wipe ija ti nwọn wa ba Ọba Kosọkọ ati Ọba Akitoye la, ti ilu si fi tutu nigbana fẹrẹ dabi ija inira loni fun ilu nkọ, ẹ ha le sọ wipe ki iṣe bẹ bi?

Bi ko tilẹ jẹ ija inira fun ilu nigbana, o ti di ohun inira fun ilu nisisiyi,

Lẹhin igbati ija awọn mejeji pari tan ni Ijọba Igẹsi ba Ọba Dosunmu ọmọ Akitoye ṣe adehun lati gba ilu, adehun ti ki iṣe adehun ti o le fun ilu Eko nijinira arara, o ṣẹṣẹ nlọ si adọrin ọdun ni, koi ti to ọgọrin debi ọgọrun ti a ni Dosunmu ba Ijọba Igẹsi ṣe adehun.

Ṣugbọn Ijọba Igẹsi yi kanna li nwọn si ndabo bo ara ilu Dosunmu ti nwọn ba ṣe adehun—titi di isisiyi, loni nkọ, nwọn sọ wipe awọn fẹ gba *Owo-ori* ni ilu yi ati ni awọn igbereko rẹ awọn *ololo ilu* si dide wipe *Owo-ori* na ko ni le wọ fun-ilu lati san, nitori ọna ti owo ngba ni ilu wo apo Ijọba ti pọju ohun ti a tun le ba wa daba lati gba owokowo kan lọ.

A sọ wipe awọn ẹniti o nranṣẹ ọja ni ilu oyinbo nsan *owo ibode*, owo-ibode yi, apo Ijọba lo nlọ awọn ẹniti o nta ọti, nwọn san owo si apo Ijọba lọdọdun, iyẹn ko ni ki nwọn maṣe san *owo-ibode* fun u ti Ijọba ba ṣe ilana nipa rẹ ni Ibode nwọn

nsanwo *Basikulu*, owo kẹkẹ ti nwọn nlo, owo *Moto* owo kẹkẹ ti nwọn fi nko ẹru lọdọdun lẹhin ti enia ba ti fi owo rẹ ra wọn tan, iyẹn ko si ni ki Ijọba maṣe gba owo ti *Bode* lori nkan wọnyi ti o ba wu wọn.

Lẹhinna ilu nsan *owo-omi* ni tulasi lẹmeji lọdun nisisiyi si apo awọn Munisiba, bi a ba tilẹ sọ ẹniti o ba nlo awọn nkan ti a ka nisisiyi ti o ni lati sanwo ẹniti o ba si fẹ ṣiṣẹ Gbanjo tita yio ma san owo lọdọdun bi awọn Munisiba ba si ṣe ibusọ si ilu fun anfani ọja tita, nwọn ko jẹ gbọjẹgẹ pe ki awọn ara ilu ma lo ibusọ na lọfẹ, ibuso ti a wi yi, gbogbo ilu li yio ma ra ọja ti nwọn ba nta nibẹ, ọna orişirişi bẹ-bẹ ni owo-ilu ngba wọ inu apo Ijoba sibẹsibẹ Ijọba taku wipe a fi bi ilu ba tun nsan *owo-ori* pẹlu.

Rudurudu ti ko ba tun şelẹ larin ilu nipa ọrọ ti a nsọ bọ ni wipe ni aseko Ọba Dosunmu awọn marun kan ditẹ si i, nwọn wa nwọn kuro ni ilu nigbati nwon nfẹ di alafia ọba ilu lọwọ, ẹnu ilu ko daradara nigbana.

Bi ilu ba fẹ daru ni igba ti a wi yi, ọba ilu pẹlu awọn ojoye yio dide nwọn a tọ Ijọba lọ wipe ki nwọn ba wọn to ilu-- Ijọba yio si gba itọ ẹnu wọn dami, Ijọba ti a wi yi ha pe meji bi? agbẹdọ, Ijọba kanna ni *owo-ori* ti Ijọba nfẹ gba yi ha le mu ilu to bi? irọ funfun patapata.

Tani ko şai mọ ninu gbogbo enia dudu ti o mbẹ ni ilẹ yi loni (lai sọ ti oyinbo omiran ti ko mọ irufẹ inira ti irufẹ owo sisan bayi le fun ilu) ti o le sọ wipe mimu ilu san *owo-ori* lagbara jẹ ohun ti o le mu ilu toro, bi a ba tilẹ ri ẹniti o le sọ ninu enia dudu ni ilẹ yi wipe ẹna ti o dara ni fun ilu ilu yi lati san *owo-ori* laduru ọna gbogbo ti a ka silẹ pe owo ngba bọ si apo Ijọba, lẹhin ti o si jẹ wipe Ijọba kọ da gbese ti *owo-ilu* si nlo si lọdọdun lai rẹhin, atilẹhin ti o le mu aitoro ilu dani ni a le sọ wipe iru ẹni bẹ nṣe, a ko so ti awọn ẹlomiran ti nwọn ngbe ara wọn ga pe awọn li awọn mbẹ nibẹ awọn lafiṣe e.

Ohun ti a fẹ sọ fun nyin ni wipe nipa gbigbe ara ẹni ga pe emi lo mbẹ nibẹ ni a fi le sọ ara ẹni di ohun ganmọ, bi koṣe ẹniti ntan ara rẹ jẹ.

## OWO-ORI NI ILU WARRI.

O ta si wa leti finrin ni ko i pẹ yi, pe lẹhin gbogbo rogbodiyan ti o şelẹ ni ilu *Warri* nipa *owo-ori* koşe *owo-ori* eyi ti a ri irohin gbọ pe nwọn di yesufa nwọn yinbo fun ara wọn lọhun.

A tun gbọ wipe şile meje-abọ ni nwọn tun fẹ yi owo na si fun wọn, a ko si ro wipe nwọn ti bẹrẹ si san owo na ni ibẹrẹ oşu yi gẹgẹ bi ipinnu ti Ijọba şe wipe nwọn yio bẹrẹ si gba owo tulasi na kakiri, bi o ba jẹ wipe gasikiya ni ti şile meje abọ ti a gbọ wipe nwọn din owo ku si gẹgẹbi ipinnu lori şile mẹwa, iba dara julọ ti Ijọba ba le gba ọran owo-ori yi yẹwo, ki nwọn si gbọ ohun ti ilu nsọ.

## IPADE OWO-ORI NI ẸPẸ.

A ri ka ninu iwe-irohin ojojumọ *Daily News* ti ọjọ kẹrin oşu April yi pe nwọn şe ipade gbogbo ilu nipa owo ori ni Ẹpẹ larin awọn ara Ẹpẹ ati Ijẹbu ibẹ, şugbọn ọrọ owo-ori na ti nwọn sọ ni ipade yi ko i ti ni ifọriti sibi kan boya o le mu iyapa ẹnu dani gẹgẹbi ti ilẹ yi, ti gbogbo ilu nkigbe pe ko dara, ti awọn gaga melo kan si nsọ wipe eyiti Ijọba ba şe ni awọn şe.

Ohun ti a ri ka ninu iwe-irohiu ojojumọ nipa ipade owo-ori na li eyi :—

### COLONY PROPAGANDA

INCOME TAX (COLONY) ORDINANCE, 1927.

It is reported from Ẹpẹ on the Eastern District of the Colony of Nigeria that the District officer had a public interview with the Ẹpẹ people at 9 o'clock last Saturday morning when he told them that the Tax will be collected either in April or in June as the Administrator may direct. That all sums of money so collected will be forwarded to Lagos; but that the Administrator has not fixed yet the amount to be collected from or paid by each person.

Bakare Kaka the Ọtun Balogun replied and asked that they the chiefs should be permitted to draw some commission on amounts collected or salaries for collecting Tax. He also asked that the amount of Tax should not exceed five shillings per head per-man.

Mọgaji Mọmọdu Shabi rose and said :— There is no money in Ẹpẹ we have no work to do from which the people can get money, Government we pray to pity the people.

Balẹ of the Ijẹbu Community said that the Ijẹbu-Ẹpẹ people whom he is the Balẹ have not yet given him their reply for the District Officer about the proposed Tax, but he beleived that as their Ramzan Festival is now over, it will not be long, before they will be able to give a reaply. If the Ijẹbu-Ẹpẹ people agree to pay, he the Balẹ should like to get his own share from any amount collected from his people.

The District Officer said the Balẹ of the Ijẹbu Community should try and get them to reply in time—the interview closed.

Ninu ipade na ọrọ ẹnikan li a ri mu dani, awọn ẹlomiran le yi irufẹ ọrọ bẹ si ọna igbojuganga, bẹ ko si otitọ ti o ju irufẹ ọrọ bẹ lọ, awọn ẹlomiran ri otitọ ti o farahan gbangba şugbọn gẹgẹbi o ti jẹ wipe nwọn kole sọ o fun Ijọba, o tunbọ njẹki nwọn ma gbe ogun kari pe awọn ko si ninu ẹniti o le şe kanrangba si Ijọba nipa ọran owo yi, lori gbogbo rẹ nibo ni irufẹ awọn ẹni bẹ yio kọju si

nigbamira fun awọn ẹbi ati ọmọ, lẹhin igbati o jẹ wipe sisan owo yi ko le da ẹnikan si, bikoṣe Gomina ti o jẹ Alakoso fun ilu.

Ọrọ ẹni ti a le mu dani ọro Mọgaji Mọmọdu Shabi, o dide o sọrọ niwaju District Officer ti o lọ ba wọn sọrọ bayi pe, ko si iṣẹ lọwọ awọn ara Ẹpẹ debi ti nwọn ti le ri owo kan san, awọn si nṣadura pe ki Ijọba le ṣanu awọn.

Ni gbogbo ilu ti Ijọba nmu alamọri owo yi lọ, ko si ibosi ohun pataki ti nwọn nke e, bikose igbe ai si iṣẹ.

Awọn ilu papa nihin iregbe ko si iṣẹ ko si ohunkohun ni nwọn nke nihin fun Ijọba, a si mbẹ wọn pe ki nwọn fi ọran owo yi si igbagbe gẹgẹbi o ti jẹ wipe irufẹ owo-ori gbigba bayi nihin kole mu irọrun ati alafia fun ilu, bikoṣe irọkẹkẹ ati aibalẹ ọkan.

Awọn Ijọba papa si le jẹri pe gbogbo ibiti awọn gbe nyan iko lọ lati lọ fi ọran owo yi lọ, iregbe ai si iṣẹ ati ai si owo ni nwọn nwi—sibẹ-sibẹ, Ijọba taku pe awọn ko ni gba ohunkohun ti ẹnikẹni tabi ti ilu kilu le sọ nipa rẹ.

Ohun ti ko jẹki a le ri ọrọ pataki kan mu dani nipa ọrọ ti Bakare Kaka Ọtun Balogun Ẹpẹ ati Balẹ awọn Ijẹbu, loju wa o dabi ẹnipe ọrọ wọn pẹlu ti Ijọba fẹrẹ papọ mọ'rawọn, nwọn ko sọ ọrọ ti o ja fun kiko ọrọ ọwọ ti nwọn fi lọ wọn sonu, o dabi ẹnipe ọrọ atilẹhin li nwọn ba Ijọba sọ, bi irọ ni, bi irọ ko ẹ ka gbogbo ohun ti nwọn sọ si ọrọ na ninu esi wọn, eyiti a ri ka ninu iwe-irohin ti a si da fun nyin, fun anfani awọn ara Ẹpẹ ati Ijẹbu Ẹpẹ to mbẹ ni ilẹ yi. Ọrọ to delẹ yi ki iṣe ọrọ pe ẹnikan lo nkọ ẹnikan, gẹgẹbi ero awọn apa kan ti nwọn nsọ wipe awọn ara Eko lo nda awọn ilu miran lẹkọ agbara pe nwọn ko gbọdọ gba fun Ijọba pe awọn yio san *Owo-ori*, Ọlọrun ṣe kosi ara Eko kan ti o yọju si ipade wọn ni Ẹpẹ, ki a ba sọ wipe boya imọran ti nwọn fi si wọn lẹnu li nwọn gbe si iwaju oyinbo *District Officer*, ti o lọ ba wọn sọrọ.

Tani ẹniti ko mọ irufẹ ipo ti gbogbo ilẹ enia dudu wa loni nipa ailọdede iṣẹ? Afi oṣika enia, afi oni tẹmbẹlẹkun ati oni rukerudo.

Bi gbogbo nkan ba tilẹ nlọ dede ni ilu Oyinbo, awa gba wipe akuṣẹ Oyinbo, a ko le fi we ti enia dudu, awọn Oyinbo nwọn ko jẹ jẹki iran wọn rare iṣẹ, gẹgẹbi awọn enia dudu ti ndaju ara wọn ti nwon ni awọn nṣọtẹ, ọpọlọpọ ọmọ wọn lo kan orin irin iranu lẹsẹ nigbati nwon ko ri iṣẹ ti nwọn ma ṣe, nwọn ko si jẹ ranti pe awọn ọmọ wọn ni ko ni lari lode yi, bi awọn tikalarawọn tilẹ ni dukiya ọpọlọpọ lọwọ.

Awọn Oyinbo papa mọ wipe kini enia dudu ni lọwọ, bi o ti wu ki nwọn le la ki nwọn le lu to awọn mọ wipe ẹhin ni ẹmọ adiẹ nto iya ẹ, ni nwọn jẹ fun wọn laisi tabi-tabi ninu rẹ. Bi awọn enia dudu ba si sun pẹtẹ ti nwọn ro ori ara wọn wo daradara pe inira ati ika li awọn ma nfẹ ṣe fun iran wọn, ṣe iba dara julọ, a wi gbogbo rẹ tan sibẹsibẹ iho eti wọn lo ngba jade si odi keji tabi bi eyi a mu odi ti a fi iṣo kan mọ ni leti pe ki a ma ba gbọ'ran—awọn papa si joye egungun adiẹ ti nwọn nba sọrọ ti o nṣe hun ! ! hun ! ! ! Otitọ melo ni Oyinbo le fihan enia dudu bi o ti wa ki nwọn le ba wọn rẹ to, bi enia dudu kan ba tilẹ nṣe fuja pe ko si bi on ko ti to larin Oyinbo Ọbọ ati omugọ patapata ni iru enia dudu bẹ, o le ba Oyinbo ṣe aṣaro ati ipinnu ọkan ko jọ ọkan, eyi ko ni ki nwọn ri ṣiri pataki kan larin ara wọn, ki nwọn sọ wipe ki oluwarẹ wa gbọ tabi ki o wa ba wọn da si i—agbẹdọ ! ! ala ti ko le ṣẹ laelae ni ala kurumọ ti o ni on ba Ọga on jẹ irẹsi pọ lori tabili.

Bi Ọga kan tilẹ fẹran ọmọ-ọdọ rẹ titi, o le sọ wipe onjẹ konjẹ ti on ba njẹ li on yio ma fun u jẹ ṣugbọn ko jẹ sọ wipe ki iwọ lọ yọ ṣibi ki on lọ fi ṣibi yọ ki awọn jnmọ wa jẹun pọ, bẹni ọrọ awọn enia dudu ti a nsọrọ wọn yi ri.

Ẹ ye tan ara nyin jẹ ẹ lọ mu ara nyin lọkan, ki o le sunwọn fun nyin lọla.

Oyinbo kan ko de ilẹ yi, ki o sọ wipe nitori owo ti ni ọpọlọpọ enia dudu lọrẹ, on ki yio pada lọ si ilu on mọ.

Bi o ba jẹ bẹ, ọpọlọpọ Oyinbo lo ti nwa si ilẹ yi ri, ti nwọn si saba enia dudu lati ma ba lọ, awọn da nibin loni.

Nigbati nwọn nsọrọ owo *Income-Tax* ni *Igbimọ* ti *24th August 1927*, gbọ awọn Oyinbo ti nwọn sọ wipe awọn mbẹ ninu pe ki *Ijọba* gba *owo-ori* na, kosi eyiti kosi labẹ Ijọba ninu wọn, Ijọba ni nwọn nṣiṣẹ fun, Ijọba lo si nsanwo wọn, ewo ni ti enia dudu ti o ni on ko fẹ ri enia dudu soju? ẹ ha le fi ẹtẹ silẹ ki ẹ ma pa lapalapa.

## GOMINA ATI ILU.

Ninu irin ajo ti Ọlọla Gomina Græme Thomson rin lọ si ọna ilẹ Hausa lati bi oṣu kan o le diẹ, titi ọjọ Alaruba ọjọ marun loni si yio de si ilẹ yi, nitorina a le ki i ku abọ silẹ.

Ohun pataki ti a fẹ sọ ni pe a tun fẹ bẹ Gomina lẹkan si nipa Owo-ori, ki o ye ki o jọwọ ki nwọn ba awọn ara ilu fi ọran owo na si ero ti ilu nfẹ, ero ti o jẹ wipe ilu le ṣe adura le lori fun Ijọba—ọna wo ni ilu le fi ṣe adura, gẹgẹbi ẹniti o ri talaka ti o nṣe irahun lọdọ rẹ pe ebi npa on ti oluwarẹ si bọ talaka na, tabi Alumọngeri ti o gbe igba bara wa si ẹnu ọna enia, ti oluwarẹ si bun ni Sara, dajudaju adura atọkanwa li talaka tabi Alumọngeri bẹ yio ṣe, fun ni.

Bẹ gẹgẹ ni ọran Owo-ori yi lọ, a nfẹ ki Gomina ṣe atilẹhin lati jẹki Ijọba fi owo na silẹ fun ilu gẹgẹbi a ti la a nisisiyi, ki ilu si ṣe adura atọkanwa gẹgẹbi talaka tabi Alumọngeri ti ebi npa li

a si fun ni onjẹ, ti orugbẹ ngbẹ ti a bun ni omi mu.

Kosi iṣẹ ati owo ni ilu debi ti ori le ya ilu lati ti Ijọba lẹhin nipa owo-ori yi—ẹ ba ilu wo ṣe o.

*God save the King, and bless His Excellency the Governor.*

Emi ni tiyin nitoto,
KEKERE AWO.

*Afiyesi:*—Lọsẹ to mbọ lagbara Sọko, ao gbiyanju diẹ lati ba ilu kẹdun ti iku ologbe Josiah Doherty ninu wosika pataki ti ao ṣe.

KEKERE-AWO.

---

## OLUSAKIN'S COLUMN.

### General House Warming.

On Easter Monday, the 9th instant, Mrs. E. J. Alex. Taylor, the kind hearted and amiable wife of E. J. Alex. Taylor, Esq., Barrister-at-Law, issued invitations to some elite in the community whom she received at mile 16½ Agege District in connection with a "general house warming" there from 10 a.m., till about 7.30 p.m. Music, Games and Dancing were indulged in. The Triumph Orchestra which was in attendance discoursed selected music.

Elaborate refreshments and drinkables from Aerated Waters to Champagne and other Liquids were liberally served. Ki Oluwa ko jẹ ki ẹ ri ẹmi fi lo ile na.

### Christening.

The Christening ceremony of the Infant child James Samuel Olaṣeni son of Mr Joseph Matanmi Shonubi and of Madam Caroline Durodọla Ayodele Coker, took place at African Bethel Church, Lagos on Easter Sunday, the 8th day of April, 1928, at 3 p.m. The Sponsors were Messrs. Phillip T. Coker, T. A. Ayodele and Janet Apọtun.

Rev. A. Aboyade-Cole officiated. Immediately after the ceremony the guests retired to Mr. Shonubi's residence 31, Princess Street, Isalegangan, where refreshments and drinkables were profusely served. We say to Mr. Shonubi E tu inawo, Oluwa a da omọ si.

### On Leave

Mr. Festus H. Lawson, Station Master, Zaria, is on one month's leave as from the 3rd April, 1928. And on the 5th April, Mr. Lawson arrived Lagos to spend part of his leave before resuming his duties.

Mr. George I. Benson of the Nigeria Regiment Office, Zaria, is on one and half month's vacation leave, as from the 3rd April, 1928.

Mr. Benson arrived Lagos on the 5th instant, to spend his leave.

### Birth

Mrs. Florence Abeke Martins, wife of Mr. C. J. Martins was delivered of a baby boy on Good Friday, the 6th April, 1928. We understand that both mother and child are doing well. Congrat.

### The Lagos Easter Race.

Easter Races held on Saturday the 7th and Monday the 9th April, 1928, at 4 p.m., each day.

FIRST DAY.

Race 1.—*The Maiden Purse,* 4 furlongs—1st Mr. A. Amalvy's, *Citroen*; 2nd Mr. Ajenifuja and Dr. J. C. Vaughan's, *Asiribo*; 3rd Mr. P. F. Pritchard's *Cargo*.

Race 2.—*The Senior Handicap,* Distance 6 furlongs—1st Messrs. Carruthers and Minaise's *Onegh*; 2nd Mr. Joseph George's, *Black and White*; 3rd Messrs. Zarpas and Mandridis, *Farin-Kafa.*

Race 3.—*The Maiden Mile.* Distance 1 mile, 1 furlong—1st Mr. Kamil Saidi's *Jupiter*; 2nd Mr. Ianko Nabawa's, *Jakishira*; 3rd Mr. G. J. Lethem's, *Nimble.*

Race 4.—*The Junior Handicap* Distance 5 furlongs—1st Mrs. A. Alakija, *Wind*; 2nd Messrs. Carruthers and Minaise's, *Say When*; 3rd Mr. A. Amalvy's, *Citroen.*

Race 5. *Nigerian Bar Plate.* Distance 1¼ miles—1st Major William-Thomas' *Queen's Royal*; 2nd Messrs. Alakija and Rhodes; *Seascout*: 3rd Messrs. Barrow and Ford's, *Bador.*

SECOND DAY

Race 6. *The Lagos Race Club Plate.* Distance 7 furlongs 1st Messrs. Carruthers and Minaise's, *Say When*: 2nd Mr. Kamil Saidi's, *Jupiter*: 3rd Mr. Ferris George's, *St. Niger the II.*

Race 7. *The Marine Cup.* Distance 5 furlongs, 1st Mrs. A. Alakija's, *Wind*; 2nd Messrs. Carruthers and Minaise's *Onega*; 3rd Mr. C. S. Honey's, *Black Reynard.*

Race 8.—*The Easter Plate,* Distance 6 furlongs, 1st Mr. Ferris George's, *St Niger the II*; 2nd Mr. Kamil Saidis, *Jupiter*; 3rd Messrs. Carruthers and Minaise's *Say When.*

Race 9.—*The 4th Battalion Nigeria Regiment Race.* Distance 4 furlongs, 1st Mr. P. F. Pritchard's, *Cargo*; 2nd Captain A. V. Welker's, *Nightmare*; 3rd Captain T. Y. Whitfield's, *Nifty.*

Race 10.—*The Chief Secretary's Cup.* Distance 1½ miles. 1st Messrs. Alakija and Rhodes, *Seascout*; 2nd Major William-Thomas *Queen's* Royal; 3rd Mr Joseph George's *Black and White.*

### Dr. Sapara, I.S.O.

Dr. Oguntọla Ṣapara, I.S.O., left Lagos for Abeokuta on Tuesday, the 10th instant, in connection with Miss Ẹdun's marriage.

### Death of Chief Sasore of Ondo.

The death of Chief Akinrinlola Ṣaṣọrẹ of Ondo is announced as having taken place at Mr. C. Ibarẹ Akisan's Farm at Agege on Easter Sunday, the 8th April, 1928, at about 2 p.m.

Chief Ṣaṣọrẹ was somewhere at Apapa Road for about two months prior to his death in the interest of his health.

The deceased was one of the most influential chiefs of Ondo, educated at St. Paul's Breadfruit School in those days.

With kind permission of the Government, his corpse was brought to Lagos from Agege on Monday and was ultimately carried to Ondo at about 11 a.m., the same day for the burial, and funeral ceremonies befitting the dignity of his position.

The late Chief abhorred bribery and corruption and was an embodiment of everything that is good, honest and altruistic. A kind father, a devoted husband to an innumerable wives and therefore an "old testament" Christian to the backbone. To all his relatives at home and abroad, and to the Executive Ondo, our sincere condolence.

### Obituary.

The death of Master Akinọla Ladẹinde, second son of Mr. J. J. Ladẹinde of 3, Wiwọ Ona Tẹrẹ Street, Lagos, is announced with profound regret. The sad event occurred on Easter Sunday the 8th April, 1928, at 3 a.m.

The funeral service took place at Wesleyan Church, Olowogbowo, at 3.15 p.m. Rev. T. J. Henry officiated.

To the father Mr. J. J. Ladẹinde and to the brothers and sister of the deceased our deep sympathy.

OLUṢAKIN.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, APRIL 14, 1928.

## PRINCE EṢUGBAYI ELEKO, "ỌMỌ" ỌBA KING.

Ninu oṣu yi ni a gbọ pe ẹjọ Prince Eṣugbayi Eleko yio di fifọnsi ni ilu Ọba; a pe Prince Eṣugbayi Eleko ni "ọmọ" Ọba King nitoripe igbagbọ wa ni pe gbogbo awa ti a wa labẹ Asia Ijọba Gẹsi ni anfani lati pe ara wa ni ọmọ abẹṣẹ Ọba King; bi ere bi ẹwa o ṣẹ nsumọ ọdun kẹta ti ẹni a nperi na ti fi Eko silẹ: ohun ti o si jẹ ohun itẹlọrun ni pe ko si igba kan ti ilu ki ngburo bi o ti wa ni alafia si ni Ode Ọyọ; a tilẹ gbọ pe ni lọloyi ni awọn Sanmari kan lọ ki lọhun: nwọn si ri pe alafia ni o wa, okuta nikan ni on ki ku 'rọju: ẹlomiran le ro pe gẹgẹbi riro ẹjọ na ti pẹ loju wọn, ko da wọn loju bi yio le tun jẹ riro mọ, irufẹ awọn enia bẹ gbagbe pe o ṣoro ki ẹjọ ti o ba ti wọ Kotu iba ṣe Kotu Ọlọpa ni o tabi Ganran, tabi Kotu abẹṣẹ Ọba King nilu Oyinbo, põra sibẹ lalai ṣe ẹjọ na ni kan, eyi bayi jẹ itẹlọrun fun ẹnikẹni lati mọ pe efufu lẹlẹ ko ni mu nkan ilẹ jẹgun, eyini ni pe ẹjọ na ko ni ṣai jẹ riro bi o ti wu ki o pẹ to dandan.

Ohun ti o jọ ohun ni a fi nwe ohun, ẽpo ẹpa jọ posi Ẹliri, awọn enia pupọ ti nwọn tilẹ ni ẹjọ ilẹ ni Kotu ilẹ yi mọ bi o ti le pẹ to ki ẹjọ na to le pari sibi kan fun wọn, ẹjọ ilẹ miran ngba to ọdun n eji mẹta ni Kotu tabi jube lọ nitorina ko yẹ ki ẹnikan kọminu pe riro ẹjọ Prince Eṣugbayi Eleko di tiratira.

Ohun ti o ku loju wa ni pe gẹgẹbi a ti ngbọ pe riro ẹjọ rẹ ku si dẹdẹ bayi, o yẹ ki gbogbo awọn olufẹ Ẹni-aiye-nlẹ yi mura adura gbigbona ati adura atọkan wa pe ki Baba maṣai pẹlu ẹjo na si atari anfani.

A woye pe ọpọlọpọ adura ni awọn enia wa yio tẹwọgba nitori ṣaṣa ni ko ti ni itara si ọrọ ẹjọ yi lati igbati rogbodiyan na ti de 'le titi o fi di oni oloni, Ọgbẹni kan mọni-mọni lo nsaba siso pe epo Oyinbo ki sun, bẹni ẹsẹ ki kun Ikõko, lọna bayi ni a fi le sọ pe ko yẹ ki ọrọ yi su ẹnikẹni nitoripe suru to to suru ni ọrọ na gba, a koi ti le sọ ju eyi lọ lakoko yi nitoriti ko yẹ ki a ṣiwaju ẹlẹdẹ: mẹlọmelọ si ni ọrọ ti o mbẹ ni Kotu gba titi yio fi pari si ibi kan.

Bi a ti nwi yi ọgọrọ lo le ti gbagbe irufẹ irọkẹkẹ ti o ti wa nigbati ẹjọ na ṣi wa ni tutu yọyọ nibi; ṣugbọn sibẹsibẹ ko si igbati iwe-irohin kan ma f'ẹnu kan ọrọ ẹjọ na ti gbogbo ilu ko ni takiji bi ẹnipe ọrọ na ṣẹṣẹ ṣẹlẹ ni.

A kan sara si awọn Lọya Prince Eṣugbayi Eleko ti nwọn ti wa nidi ẹjọ na ni ilu Ọba lati ojọmijọ yi wa: nitotọ ẹlomiran le sọ pe "ṣe iṣẹ owo wọn ni nwọn nṣe", bẹni; ṣugbọn ẹniti a fun niṣẹ ṣe ti o si mura lọtun losi lati bojuto iṣẹ na, papa ni ilu okere-rere bi ilu Oyinbo, ọga ni oluwarẹ; owe wa lo sọ pe ẹniti o ṣe oju ko ṣe, bikoṣe ẹniti o ṣe ẹhin: eyi si jẹ ẹkọ fun ọpọlopo enia pe diduro ti nkan lai yẹ ẹsẹ jẹ ohun ti a le kan sara si.

Lẹkansi, ẹnyin ilu, ẹ ranti ọrọ ẹjọ yi ninu adura nyin —Aṣẹ ti Edumare!!

---

## TANWIJI, YANMU-YANMU.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU ]

Mo bẹrẹ f'oji,

Orişirişi ọna ni awọn Munisipa (Municipal Department) fi ngba owo lowọ Ilu, ka to san owo ile, ka to san owo omi, ki to fi owo ra kẹkẹ ologere (*Bicycle*) ka to tun fi owo ra yago-l'ọna, ninu igbe ko s'owo ko s'owo ti gbogbo ilu nkẹ nisisiyi. Owo ko lo dede mọ, ọpọlọpọ onişowo di onigbese, Oyinbo ndin owo ọja ku diẹdiẹ ni Şabu, Ijọba nda Akọwe duro, ile ti nwọn ti nhaya ri ni poun mẹrin loşu di poun meji abọ, pẹlu bi gbogbo nkan ti ndin owo ku diẹdiẹ yi, nitori ibajẹ owo sibẹ sibẹ anu enia ko ṣe ọga awọn oyinbo oke-odo, *General Manager Nigerian Railway*, lati din owo ọkọ *Railway* ku, ati owo ẹru wiwọn.

Nigba pupọ ni a nri awọn obinrin to nṣe wahala lọ si Agege, Oşodi, Alagbado, ati ibomiran lati lọ şe owo pẹpẹpẹ nibẹ, şugbọn pẹlu gbogbo wahala wọnyi, melo ninu wọn lo le wọle ko jade

nigbati inawo ponwun meji pere ba yọ si wọn lọjọ? Iba ere diẹ kiun ti iba bọ si apo wọn, o ti bi owo ọkọ ati owo ẹru wiwọn lọ. Bi enia ra ... lati fi ranṣẹ si Kano, tabi Ororo-Ẹpa lati Kano ... si Eko fun tita, lẹhin ti oluwarẹ ba yọ owo to ... ra wọn kuro, to si yọ owo ọkọ ati owo wiwọn kuro, eyi to ku gbese ni. Njẹ, kini anfani *Railway* tabi ọkọ ilẹ ti ko ṣe ilu ni rere?

A si wadi soke, sodo, kini nwọn ti nṣe gbogbo owo ti *Railway* ngba; a ri pe ogoro ninu rẹ lo nba owo iṣẹ oṣoṣu awọn Oyinbo lọ, laika eyiti nwọn fi nsan owo ọkọ wọn lọ si ilu Oyinbo. O ... ki *Nigerian Railway*, mọ pe inakuna pọ nibi iṣẹ ..., nigbati Colonel Hammond ba si jihin iṣẹ rẹ ... nilu Oyinbo ni lọlọyi, o da mi loju gbangba pe, ọpọlọpọ igi ti ko ba so eso rere ni *Railway*, l'a o ke lulẹ, ti a o si wo sinu ina.

Bi *Nigerian Railway* ti ṣe eti gbọin s'ọde, ti awọn si nṣe aigbọran s'eṣu yi, bẹni o dabi ẹnipe awọn Munisipa ko bikita lati din diẹ ku ninu orişirişi owo ti nwọn ngba lọwo wa. Lati şile meji abọ, owo iwe (*License*) kẹkẹ ologere (*Bicycle*) fo fẹrẹ lọ di şile mẹwa lọdun, bi enia si fẹ lati pa Ewurẹ, Agutan tabi Malu jẹ nile rẹ, o ni iye owo ti o ma san fun awọn Munisipa ko to le dunbu rẹ. Lati le tọju ilu bo ti to, ati bo ti yẹ daradara, Munisipa ni lati l'owo lọwọ: şugbọn anu şe ni pe won ko tun ilu şe to bi nwọm iba ti tun şe. Ti a ba yọ ọwọ opopo ọna Ẹhingbẹti, Ẹhin-ọgba, Broad Street ati opopo miran ti Oyinbo ngba nigbakugba kuro, adugbo pupọ ni Ilu lo nfẹ itunşe ati itoju. A ko le şẹşẹ ma daruko gbogbo adugbo to nfẹ itunşe bayi, nitori ko si ibiti awọn Wole-wole (*Sanitary Inspector*) ko mọ ninu gbogbo wọn.

Tanwiji to wa loju gọta (*gutter*) ita ẹlomiran ati ẹyiti o wa ninu adagun omi to nrun ni'ta gbangba l'adugbo ẹlomiran ju ẹgbẹrun okẹ lọ. Awọn Wole-wole ko npe Ijọba tabi Munisipa l'ẹjọ nitori wọn; şugbọn je ki nwọn şeşi ri ẹyọ Tanwiji kanşoşo pere ninu Ileko Sẹlia tabi ti Aşimọwu rẹrẹ, o di Kotu (*Court*) rẹrẹ. D po eyiti Onidajọ iba da sẹria Sisi tabi Şile kan fun wọn, a ni ki nwọn lọ san Şile marun, Şile meje abọ, Şile mẹwa bi ẹni wipe nwọn le fẹ Tanwiji tabi Yanmu-yanmu ku ni'le on papa.

Ẹda Olorun ni Tanwiji ati Yanmu-yanmu jẹ; gbogbo Dokita Eko ati ti ilu Oyinbo ko si le le wọn kuro l'aiye. Nwọn ki nşe Orşa ti Enia Dudu le bọ, bẹni wọn ko nşe Cocoa tabi Ekurọ ti a le ta fun Oyinbo l'ẹhingbẹti; sibẹsibẹ, alalẹ ni a ngbọ orin aro wọn pẹlu ẹbẹ ati ijakadi lati wọ abẹ apo (*Mosquito Net*) ti a nsun si.

Orişirişi Tanwiji ti Oyinbo npe ni *Bacteria* tabi *Germs* lo pọ l'aiye gẹgẹ bi oniruru eweko igbẹ; şugbọn diẹ kinun ninu nwọn lo le şe enia ni amba. Bi eyikeyi ninu awọn diẹ yi ba si wọ inu ara lati pọ oro sibẹ, ijakadi diẹ kinun ko ni *White Corpuscles* tabi ẹjẹ funfun nba won ja lati pa oro wọn; şugbọn nigbati o ba şe, agbara ẹjẹ yi yio ma din ku diẹ-diẹ, nitorina ni a şe ni lati ma wa ni mimọ ati li aileri nigbakugba, ka ma si şe jafara ati kesi Dokita lakoko aisan.

Şugbọn Dokita to ba wipe ko si eyiti o dara ninu gbogbo agbo, agunmu ati egbogi wa miran, o npurọ ni. Amuyo ati amuju laisi iwọn lo nba egbogi wa jẹ. Nitorina, yio jẹ ohun daradara fun awọn Dokita wa lati kọ egbogi ti ilẹ wa ni akọye; eweko igbẹ, irufẹ eyi ti a nta l'Ọbun Eko la fi şe ọpọlọpọ egbogi Oyinbo; eso lara ni a fi nşe *Castor Oil*, Ata pupa ni *Pain Killer*, Oruwọ ni *Quinine*. Lakoko arun ayọkẹlẹ (*Influenza*) mo şe ki epo pupa lasan pẹlu Ewe Asoṭẹiyẹjẹ ati Ewe Rere lo wo ọpọlọpọ enia san.

Ju gbogbo rẹ lọ, owo ti Kotu ngba nitori Tanwiji pọju, o yẹ ki *Nigerian Railway* din owo ori ọkọ ati owo ẹru wiwọn ku, o si tun to, ẹwẹ, ki awọn Munisipa din diẹ ku ninu orişirişi owo ti nwọn ngba lọwọ wa, ode le.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

---

ORI III.

## IWA—ẸGBẸ KIKO ATI APẸRẸ.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KẸRIN.

Lọna gbogbo laiye, iwa ni o ju.

Ninu ile-işẹ, enia ti o ba ni iwa rere a fi iwa rẹ ran awọn oşişẹ ẹgbẹ rẹ, a mu wọn ro ero rere. A gbọ pe nigbati Franklin wa ni Oşişẹ ni London, o mu iwa gbogbo awọn oşişẹ ti nwọn jumọ nşişẹ, ko ku ọkan, yipada si rere. Bẹna si ni enia buburu oniwa jagbajagba, ko ni mọ titi yio fi sọ awọn ẹlẹgbẹ rẹ di enia lasan ati oni jagba-jagba. Captain John Brown—ti a npe ni "ma "sọ ẹsẹ" Brown ("*marching on*" *Brown*)—sọ fun Emerson ni ọjọ kan pe, "Fun ajeji ti o lọ mu ilẹ ni ilu ti a şẹşẹ tẹdo, enia rere ati onigbagbọ kanşoşo kun ara to ọgọrun, o tilẹ to ẹgbẹrun awọn enia ti ko ni iwa." Apẹrẹ iwa rẹ gberan tobẹ ti o fi ran gbogbo awọn iyoku fun rere, o si mu wọn di ẹniti o ni akanloju işẹ bi ti on papa.

Biba enia rere lo pọ ki iṣai bi ire.
Oniwa rere a fun iwa rere rẹ kakiri.

Ninu awọn alọ awọn ara ilẹ orun, ilẹ kan ti o nja firi—olorun didun, dahun o ni, "Erupẹ lasan ni mo jẹ, afi igbati a gbin awọn itana sinu mi." Iya ọbọ, ọbọ, no a si bi ire. Cannon Moseley ni "ọpọlọpọ ire ti ire-ṣiṣe nmu wa ya ni lẹnu. Ko si ohun rere kan ti o da do, ko si ohun buburu kan ti o da do; a sọ awọn ẹlomiran di rere tabi a sọ awọn miran di buburu—awọn wọnyi a si tun ṣe bakana, bẹ bẹ titi lọ: o dabi okuta ti a sọ si arin odo ti imu omi ka ribiti; ribiti yi a si tun ṣe ribiti miran ti o tobi ju ti akọkọ lọ, bẹ titi lọ de eti odo x x x. Mo ro pe gbogbo ire ti o wa laiye fẹrẹ jẹ pe lati ọwọ d'ọwọ lati aiye b'aiye ni nwọn gba kan wa, pupọ wọn ni o si ti orisun rere ti a ko mọ wa."

Bẹna ni Mr. Ruskin sọ pe "Eyiti ibi ba bi, a bi ibi, eyiti akin ati ọmọluwabi ba si bi, a kọ ni ni iwa akin ati ọmọluwabi."

Nitorina ni o fi jẹ pe iwa ti olukuluku enia jẹ apẹrẹ iwa ti awọn ẹlomiran nkọ lojojumọ. Bi iwa enia rere ti jẹ apẹrẹ ẹkọ fun awọn ẹni rere, bẹ ni o si jọ ibawi nlanla fun awọn enia buburu.

Dr. Hooker ṣe akajuwe iwa oniwasu kan ti o jẹ enia rere, ọrẹ rẹ pe, iwa rẹ dabi "oro didun ti a nfi oju ri", eyiti imu, ani, enia ti o buru ju gba pe adun wa ninu iwa rere.

Bẹna si ni George Herbert, ẹni rere, sọ nigbati o bẹrẹ iṣẹ iwasu ni Ijọ ti nwọn yan si: "Ju gbogbo rẹ lọ, emi yio hu iwa rere, nitoripe iwa oniwasu ni iṣẹ iwasu ti o lagbara ju, eyiti imu gbogbo ẹniti o ba ri i, ni ọwọ ati ifẹ, bi ko tilẹ ṣe gbogbo rẹ, a mu ki nwọn ni ifẹ lati hu iwa bi tirẹ." O wa so pe "Eyi ni emi yio si se, nitori mo mọ pe, ni aiye isisiyi, apẹrẹ iwa rere yio ṣe wa ni ire ju ẹkọ enu lasan lọ."

Alufa ẹni rere kana yi ni, ni ọjọ kan nigbati nwọn nba wijọ pe o ṣe ore kan fun ọkọnrin talaka kan ti nwọn ro pe ko to ẹniti ide sakani alufa yi, esi daradara ti o fi ni pe ero pe on tilẹ ṣe irufẹ ore bẹ "yio jẹ iro orin didun fun on ni ọganjọ oru."

Izak Walton ni o sọ fun nipa ti iwe kan ti George Herbert kọ ranṣẹ si Bishop Andrewes, iwe na sọ nipa ti iwa mimọ. Bishop Andrewes "fi iwe yi tẹlọ ara labẹ aṣọ rẹ", bi o ba si yọ jade ti o fi han awọn ti o nkọ ni ẹkọ, "a tun da pada si ibi ti o ti yọ, o si wa nibẹ, ni ọkan aiya rẹ titi o fi ku."

Agbara iwa rere bi onfa ati bi amunimuye, ko kere. Enia ti o ba ni i, on gan ni Ọba laiye, ti ima mu ọkan gbogbo enia fa si tirẹ.

Nigbati General Nicholson gbọgbẹ ti o nku lọ ni Delhi, o fi ohun ikẹhin ṣọwọ si ọrẹ rẹ Sir Herbert Edwardes, ẹniti o jẹ ọmọluwabi ati akọni bi on papa, o ni: "Sọ fũn pe, iba dara fun mi pupọ bi o ba ṣe pe nko ye bã gbe pọ, ti ko ba si ṣe ti iṣẹ ilu ti a nṣe, ti ko fun mi ni aye lati ma rin tọ ọ. Ko si igba kan ti emi wọ ti on ati obinrin rẹ, bi o ti wu ki nma pẹ lọdọ wọn to, ti ibagbepọ wọn ko ṣe mi ni ore. Ki awọn mejeji fun mi!"

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-OSA

---

KA TO RI ERIN O DI IGBO, KA TO RẸFỌN O DI ỌDAN KA TO RẸNI BI DOHERTY, LODE EKO O DI IGBAKAN.

[ LATI ỌWỌ ỌMỌ AWO ]

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Popo enia le wi pe kini ṣe ti afi sọrọ Ọgbẹni Doherty to yi mnu *Eko Akete*, ṣugbon laiṣiye meji ngo rẹni meji tabi mẹta ti o ma da oluware lohun pe, bi a tilẹ fi ojojumọ nsọrọ Ọgbẹni Doherty e tobẹ o si jubẹ lọ. Ọgbẹni Doherty, jẹ enia kan to fẹran isin pupọ, mo ro pe, ki nṣe Doherty ni kan ni o koko ni owo l'Eko. mo ṣe bi, awọn elomiran tun ni, bi tirẹ, e ha ṣe ti nwọn ko le nawo si Ile Olorun bi ti Ọgbẹni yi, ẹṣini olobinrin pupọ la pe Ọgbẹni yi, eegẹ bi a ti gbọ ni ijẹsan pe Ọgbẹni na fun *Church* rẹ ni ẹgbẹrun pọun meji eyi to jẹ pe o ti fẹ san tan ko to jẹpe pe Olodumare, a si tun gbọ pe o fi aṣẹ silẹ pe sisan ni owo na, njẹ mo tun

bere pe o ha je pe ko tun si ẹlomiran mọ to le ṣe idaji tirẹ bi ko sile ṣeto, ẹ kọ ha mo pe *Tẹni ohun si lẹni*, iyẹn ni pe ara ilu Eko ni Doherty, awọn si je atọhun rin wa, kọ ma ye nyin, bi iru ero bẹ ba wa ninu enia kan ti fi ntẹ Ilu Eko ni Itẹkutẹ, o ku oluwarẹ pẹlu Sati, nitoripe Ilu Eko yi ni gbogbo awọn ti dide tọmọlọmọ bi akara iyẹn bẹ. Ni igboro Eko yi ṣaṣa enia kọ ni iku Doherty ko dun, awọn ọmọ ọlọmọ to ran lọ si Ilu Oyinbo ni iku rẹ ko ni dun ni, tabi ẹni to jẹ gbese ti Doherty san gbese na fun, tabi awọn alaini, alagbe ati awọn bẹbẹ ti inbo ni ko ni dun ni tabi awọn wo ha ni, nitorina, awa ki awọn ọmọ rẹ ku orire, enia lo ma ni owo bi Doherty to je pe nigbati o ba ṣe aisan bẹ, popọ owo a tan, tabi bẹkọ, a di nkan omiran ko to ku Oluwa ko ṣọ ni ninu rẹ, Doherty ọrun re, ko fi owo tirẹ mọ ti ara rẹ nikan ani tẹru ọmọ lo nna owo fun enia lo sa wa ni ode Eko ni ko le kọ ọmọ rẹ niwe debi o ma ran lọ si Ilu Oyinbo, pẹpẹsẹ ani nitoripe on pẹlu lagbaja ko rẹ, njẹ ti o ba ma ṣe bẹ, ewolewo ? Iku Doherty nkọ iwọ ẹni bẹ pe, ti tọju lọmọ ki wọn ma ma dide si ọ ni ikẹhin ọjọ.

Doherty ko ku sisun lo sun nitoripe ti a ba si nri awọn ọmọ rẹ, lokunrin lobinrin ti o ti fi ọwọ ararẹ kọ debi ti ẹru ko ni ba wọn. O yẹ ka ma gbe di nilẹ fun Doherty ni isalu ọrun ṣaṣa enia lo tọju ọmọ to Doherty, Itan ilu iwa bẹ si ṣọwọn larin awọn agbalagba wa. Oluwa ko sanu wa, ko jẹ ka ku nigba to ma yẹni, ka ku lọmọde ko yẹni san ju ka dagba osi lọ, lotọ awa gba pe ọmọde si ni Doherty nitoripe ko ti to idaji ọdun iya rẹ ko to ku, ṣugbọn ẹgan ni hẹ. Iku yẹ, o si da wa loju pe bẹni awọn Angẹli yio tẹwọ gba lọrun lọhun, nitoripe o ti ṣe iṣẹ ti Baba ran. Lẹnu didun kọ, enia si nwọ nile Doherty deni, bẹni lEko yi na ni ati sin oku awọn kan, ani ka to de'le agadangodo ti so mọ ẹnu ọna ile wọn. ki nṣe pe nwọn jẹ gbese, awon lowo sini, nwon si tun ni ọmọ pupọ pẹlu, ki enia mọ iyẹn bẹ, ani o yẹ Doherty dọrun nitoripe niṣe ni ọmọ yida ẹnikẹni si jẹri si eyi, iku rẹ si jẹ pataki ninu gbogbo oku olowo ti a ti sin lEko. Ki awa sa to fun arawa wayi o, aisi owo lọwọ, lo nmu enia di mọ obinrin kan ṣoṣo titi aiye, bi o ba wa di rẹ dada ko si owo ni, ayisi owo lọwọ lo si mu awọn enia ti o nṣe ofin olobinrin kan, ani ṣaṣa awọn aya ologbe Doherty lo ma ni Doherty ko tọju on, a ko gbọ pe aya kan lọ fẹjọ rẹ sun ri afi eyiti o ba ṣe aṣemaṣe fun ararẹ, a si gbọ pe, ko si nkọ àṣá a nna obinrin bi awọn olowo omiran ti ma nṣe, ngbọ obinrin to ba ba gbele kọ lo ma na ju gbogbo rẹ lọ, Doherty ku, iṣẹ rere rẹ si ntọ lẹhin, ko si ẹnikan ti o sọ ọrọ rẹ ni buburu ri, eyiti to lati kọ ẹnyin olowo iyoku lati mọ iwahu, ki ẹ si tọju awọn ọmọ nyin, ẹ ma ṣe jẹ ki awọn ọmọ nyin lalaṣi. Nitori gbogbo iṣẹ nyin ni ẹ o jihin ni ọjọ ajiude. O ma njẹ ohun ti o nṣe wa lanu pupọ nigbati a ba nri awọn olowo miran ti nwọn ko ri ra ọmọ wọn, bẹni awọn lo ko ọmọ na jade, ni ọjọ kẹsan, ọmọ miran a fẹ ko iwe, ṣugbọn nigbati ko si oluranlọwọ kini ko ṣe o, bẹni Baba ti a nwi yi ni lọwo, iru awọn ẹni bẹ gbagbe pe Ogo wọn lati ọdọ ọmọ wọn lo ti bẹrẹ, ko si da mi loju pe iru awọn bẹ fẹ ọmọ raara awa le wi pe, aṣiri lo mu awọn ọmọ bẹ bọ sinu ọkọ wọn waiye awọn olowo miran ma rope, ti awọn ba nawo, owo na yio tan, iru awọn enia bẹ nko ọrọ jọ ni. Wọn ko si mọ ẹniti o ma ko wọn lọ, alagba kan sọ fun ni pe, o le ni ogun ọdun ti Doherty ti nran ọmọ ọlọmo lọ silu Oyinbo, ki awọn ọmọ tirẹ to to lati ran lọ, bẹsini iṣẹ rere omiran ti Ọgbẹni yi nṣe nigbesi aiye rẹ, ani kaka ki owo tan nkọ, niṣe ni o tubọ npele si—Doherty mo gba fun ẹ lọna ọrun.

J. Henryson, ṣe eyi to le ṣe, o ku sowo emi ati irẹ. Akin : o ha dakẹ ni, gẹgẹ bi ọkunrin akọbi Ọgbẹni Doherty, o ko ha ni ṣusokoto ko mura iṣẹ Baba lati ṣe, ẹru na wa lori iwọ ati aburo rẹ Bayọ, ibi ti ẹ ba gbe tẹsi ibẹ na gan ni awọn iyoku yio tẹle nyin, ẹ mura giri lati tubọ gbe orukọ Baba nyin ga ju igba ti on papa wa laiye, ki J. Henryson papa ba le rẹrin muṣẹ lọdọ Baba lọhun, ki o si wipe ẹ gbere ẹnyin ọmọ mi Alabukun ni fun nyin. Bi o ti dara Oluwa lo mọ, ṣugbọn o dọwọ nyin, O ṣe ! Ijalẹ, Doherty lọ, ko si alabasọ mọ, kini ka tun wi Ọgbẹni Ogunlaiye Josiah ṣẹ bẹ dẹni orun aremabọ, ẹniti ko fi ọrẹ ati igba kekere rẹ silẹ nigbakan titi o fi di ọjọ iku, o ṣe, ọjọ ti Ọgbẹni P. A. Williams, oninure lọ, Ọgbẹni German Martin, Doherty ko dẹ ṣemọ eyi to ku dọwọ nyin, bi ẹniti nṣe oju ẹ mura lati ṣe ẹhin, Ọba na yio ran nyin lọwọ. Njẹ awa ki gbogbo awọn aya Doherty ati ibatan rẹ gbogbo, afi gbogbo awọn ọmọ rẹ, Oluwa ko ṣọ nyin pọ. A si tun ki nyin ẹnyin ara Ibadan ati awọn, ara adugbo Alakoro.

> "Doherty sunre ko si ma simi :—
> Gbori rẹ laiya Olugbala rẹ
> A fẹ ọ—ṣugbọn Jesu fẹ ọ ju
> Sunre-sunre-sunre."

Ah iku doro, to mu Henryson ti wa lọ iku ko ba gba owo, a ko ba san ẹgbẹrun mẹwa, melo iru rẹ ti o ti fi ṣe inu rere saiye.

Bi ọrun ba jẹ ọkanna jiṣẹ wa fun awọn Baba ati Iya rẹ ọwọn, o digbere, o si tun darinako, o di oju ala, ko to tun ri Josiah ti wa, *Goodbye*.

Emi ni tiyin nitotọ,
ỌMỌ AWO.

## ẸNI ỌMỌ SIN LO BIMỌ, ỌMỌ LAYỌLE.

Lati ọwọ Riro nt'enia ṣiṣe ni ti Ọlọrun.

A dupẹ lọwọ Ọlọrun Oluṣe ohun gbogbo pe a ni anfani lati ba wọn de ibi oku Ọgbẹni Oniwarere yi, ani Ọgbẹni Doherty ti o ṣe alaisi ni ile rẹ Campos Square, ni Satide ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu tó kọja (24/3/28). O ya ẹnikẹni lẹnu nigbati a gbọ pe Ọgbẹni yi pa ipo da ni ọjọ yi, Oṣe! nijọ ti a ba ku ni a dere enia ko sunwọn laye, bo lẹwa bo ba lowo nijọ iku a di yanpon yanrin. A ki awọn ọmọ oloku wọn ku irọju baba won o, ki Ọlọrun gbe si afẹfẹ 're o.

Kini a le sọ nipa Ọgbẹni wa yi, bi a ba ma wi nisisiyi nkọ? A wi pe olowo ni Mr. Doherty, lotọ, lalai ko ṣe ani-ani olowo ni Doherty, ṣugbọn kini pataki ohun ti a wa nsọrọ ba ni pe awọn ẹlomiran wa ti o jẹ pe olowo gẹgẹbi Ọgbẹni Doherty ti nwọn ko ni iwa tabi ki nwọn lo owo nwọn na lọna ẹtọ, ẹlomiran ni tirẹ fun ọlẹ tabi ipalara ọmọ ẹnikeji rẹ, ki a ma ṣe wipe iru ẹni bẹ lowo, nitori kini a ṣe wi bayi, enia miran ti oju tọrọ (3d) npọn ti o wa titi ti ko ri, nigbati o ba wa ọna ti ko ri agbara rẹ, a tọ awọn olowo wọnyi lọ pe ẹ gba mi loni ko si kọbọ kan lọwọ mi, emi ko ri ohun jijẹ, ẹ ṣanu fun mi, nigbati olowo miran ba wo titi a wipe iwọ ọlẹ yi ni nma fi owo mi fun to ma lọ patapata ti nko ni ri ẹ mọ, jọwọ ma ba tirẹ siwaju o, ko si owo lasiko yi a fi to ba di igba miran, ki a ma tilẹ ba lọ titi, gẹgẹbi iwa ti enia ba ni ti ma ntọ lẹhin to, ẹnikẹni to ba lọ si Itẹ Oku nibi oku Ọgbẹni Doherty yi lọjọ Sunday ọsẹ to kọja na, oluwarẹ yio mọ pe iwa rere ni ọṣọ enia. Ko si botiri ni ọjọ yi ni Itẹ Oku, enia pọ tobẹ ti ko si aye lati wọ inu ọgba lọ ba wọn sin oku, nigbati o ṣe ẹnu ọna ọgba papa faya, ẹ maṣe jẹ ki o ya nyin lẹnu bi a ti wi, pe ha, bawo ni irin ti ṣe le ya, ara, ọpọ enia lo njẹ bẹ, melomelo enia to ti ku nilẹ yi, mo ṣe bi a ri bi nwọn ti nsin won lọ si itẹ, ki a tilẹ da silẹ ka tun ṣa Ọgbẹni Doherty ko si ninu abuku fun ẹnikẹni, bi a ti wi pe ede ko yede wa ni Ilu Eko yi to yi, Ọgbẹni Doherty ko si ninu Ọtẹ na bi ẹ ba wi pe o kun, o kun ni fun u, bi ẹ ba si wi pe o fa, o fa oṣe! ehin kan ile, Erin wo, oninu rere lọ, a b'ọmọ bi Eṣu, ilẹ mu enia rere jẹ, a ki gbogbo awọn ọmọ oloku, baba nsinku, ẹ ku aṣẹhinde, ki Ọlọrun jẹ ki ẹhin oku dara o, a ki awọn *Lawyer* ati *Doctor* adura wa ni pe ki Ọlọrun sun ẹmi yin si waju o, a si tun ni gbẹkẹle pe awọn ara wọnyi yio ṣe itọju awọn ọmọ lẹhin wọn dada, ki Ọlọrun mu ero atunṣe na wa si inu yin. *Amin*

Emi ni tiyin

Riro n'tenia ṣiṣe ki ti Ọlọrun.

## OFEREFE.

A ki ẹnyin ara ilu ẹ ku afojuba ọkọ oferefe eyi ti o wa si Eko ni ọjọ Wednesday ọsẹ yi ti ṣe 11th April 1928. Eyi to jẹ pe t'ọmọde t'agba lo nwo loke nigbati ariwo gboji kan to si nra baba bi ẹiyẹ awodi. Olukuluku si lọ fi onjẹ oju fun oju nipa ariwo nlala to gba Ilu kan, bi o ti jẹ ohun ara to kosi botiri ni awọn enia lokun Magacene la ti tun lọ ri idi jfin koko, ṣugbọn ko si aye lati sunmọ idi rẹ papa. Oyibo ṣe ohun ara, a ki Sir Calbon K.C.M.G, to mu ọkọ na wa ati aya rẹ.


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo Kessler ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

# Iyin Oluwa Medicine Store

**K. B. SAVAGE,**

CHEMIST & DRUGGIST

STOCK :—

## YARO

***The oldest and best Infants Preservative 1/6d & 3/-.***

## WIRELESS FEMALE PILLS

***The scientific preparation for all monthly Disorders peculiar to Females. 4/6d per bottle.***

## KADUNA BALM

(IPARA AWO'GBA ARUN).

***Can be applied in 100 different ways!!! 1/-.***

## Write or call at :—

88, Broad Street, Lagos,

6, Martins Street,

41, Alli Street, Faji Market,

109, Griffith Street, Ebute-Metta.

**Watch this space every week.**

## White's Golden Male Tonic
DOUBLE STRENGTH).

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

REMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ęda ati gbogbo arun ti ki ję ki ọkunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işę ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splendid Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq. 41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun Alroyun, Iju, Ęda, Aran, Oyun ti o ba fę baję, ati orişirişi arun mi ti ki ję ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S
## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq. 41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe, awọn ti o nfi iwe şişę ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lo fun idanwo.

*Iba şe ọmọde labi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA ĘJĘ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rę mo (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba rọ to. Aşe Ewurę pipọju, Ęda ti o ba gbo, Ęyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ęsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## *ILE OWO OYINBO*

# JOHN RADCLIFFE

Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

——— : o : ———

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ oriṣiriṣi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ loriṣiriṣi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE De[illegible] 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.